Bibeli fun awon omode

# Esekieli: Okunrin ariran



Akosile lati owo: Edward Hughes

Ayaworan: Lazarus
Alastair Paterson

Olu'lo: Ruth Klassen

Atunmo ede: Oluwashina Oluwadimu

Alakoso: Bible for Children
www.M1914.org

©2023 Bible for Children, Inc.
Iwe ase: Oni ase lati se atunko tabi attune itan yi,
niwon igba ti o ko so di owo.

Lojo pipe, Ologun alagbara koju Judah, won ko opolopo omo Olorun pada si Babiloni gege bi eru.



Jinna si ile, awon Juu yii n gbe leba odo seba. Lara won ni Iranse Olorun, woli Esekieli.

Lojo kan, Olorun fun Esekieli ni iran. Ogo Olorun farahan gege imole to mole, ninu awon eda alaaye. Okookan won ni oju merin ati iye merin. Loke won ni ite sapire ti o rewa ti o kun fun imole bi monamona. Nigbati ti Esekieli rii, o doju bole.



Olorun ba Esekieli soro, “Emi n ran o lo sodo awon omo Isireli. So oro mi fun won, won je eleti kunkun.” Owo kan farahan, O gbaamu edidi mu “Je eyi” Olorun wi pe “Lo, soro fun ile Isireli.” Iru ase woni eyi! Sugbon Esekieli gboran.



O je ninu re, o si lo.

Emi Olorun gbe Esekieli lo si igbekun awon Juu ni ibomiran legbe odo seba. Fun ojo meje ni o fi joko ti won, iyalenu ni ohun ti o ri, Olorun fi Esekieli se oluso. O ni ki o kilo fun awon eniyan ki won mase se aigboran si Olorun.





Esekieli se ohun to yato lati je ki oro Olorun ye awon eniyan. O ya aworan Jerusalemu si ori amo. Boya awon eniyan n wo ejika re nigba ti o ya aworan alagbara omo ogun yika Jerusalemu. O n fihan pe ilu mimo Olorun yoo segbe laipe.

Isireli, Ijoba Gusu, saigboran si Olorun fun irinwo odun o din mewa, ati Juda, ijoba ariwa, fun ogoji odun. Idi niyi ti Isireli parun ti Juda yoo si wo laipe, Olorun so fun Esekieli ko sun ni egbe osi fun irinwo ojo o din mewa, ati ni egbe otun fun ogoji ojo, lati ran awon eniyan leti odun ti won ti n dese.





Boya awon eniyan naa bere si ronu pe Esekieli je ajeji okunrin.  O se ohun gbogbo ti Olorun ni ki o se.  Lojo kan, o fa ori re, o si sun ida meta ninu re.  Eyi ni lati fihan pe ida meta ninu awon eniyan ni Jerusalemu yoo ku pelu aisan ati iyan nigba ti awon omo ogun Babiloni ba koju won.



Esekieli mu irun meta miiran o gee pelu ida.  Eyi ni lati fihan pe ida meta awon eniyan yi o ku nipa ida ota.  Ida meta ti o keyin, Esekieli fonka sinu afefe. Sugbon o so die ninu irun re mo eti aso re gege bi ami pe Olorun yoo pa awon eniyan re kan mo, yoo si da won pada si ile ileri.



Woli onigboya yii so fun awon igbekun Juu pe nnkan yio pada buru jojo, koni dara bi won se lero. Awon eniyan naa binu si Esekieli, sugbon ko pa enu re mo lati soro Olorun. Lojo Kan, nigba ti o joko laarin awon agbaagba Isireli, Olorun fi iran han Esekieli. Ninu iran naa, Olorun gbe e soke pelu irun re o sigbe e lo si Tempili ni Jerusalemu.



Ni Tempili, Olorun fihan Esekieli ohun ti nrako, eranko aimo, ati orisa.  A ko gbodo ri eleyi ninu Tempili Olorun.



Awon adari n sin eyi dipo Olorun. Olorun tun fi han Esekieli pe ogo yi o kuro niTempili eyi ti yoo parun. Nigba ti iran naa pari, Esekieli so fun awon Juu nipa re.





Gbogbo ohun ti Olorun so wa si imuse. Jerusalemu parun, opolopo eniyan segbe. Nigba ti awon Juu ti o wa ni Babiloni gbo, o ya won lenu pe Olorun ti ko awon eniyan re sile pata.

Sugbon Olorun fun Iranse re ni ise miiran. O mu Esekieli lo si ibi ti o kun fun egungun gbigbe-egungun eniyan.



“Omo eniyan, nje egungun wonyi le ye?” Olorun bi Esekieli “OLUWA Olorun, Iwo lo mo” Esekieli dahun. Beeni egungun gbige ko le ye mo. OLUWA wi pe, “sotele si egungun wonyii, ki o si wi pe ‘iwo egungun gbigbe, gbo oro OLUWA! Iwo o ye’”. Nigba ti o gboran, Esekieli gbo ariwo ti n kan daru. Kin ni o ro pe o fa eyi?



Nigba ti woli naa n wo tiyanutiyanu, ara wojopo egungun si egungun.



Nigba naa, eran wo to ara won.



Awo bo won, sugbon ko si eemi ninu won.



OLUWA wi pe “sotele, omo eniyan si wi pe lati igun mererin iwo eemi. Mi si won ki won le ye,” Nigba ti Esekieli se bee-eemi wasinu won. Won ye, won si duro lori ese won. Omo ogun nla kun inu ogbun naa.



Olorun mo pe ko si ireti fun awon Juu ti Babiloni nigba ti Jerusalemu subu. O ran ise lati inu iran Esekieli. “Awon egungun wonyii ni ile Isireli, Olorun so bee.” Emi o fi emi mi sara yin, emi o si fi yin si ori ile yin.



Iru ise ireti nla wo ni eyi lati odo Olorun! Ileri Olorun lati ipase Esekieli wa si imuse nigba ti a da awon Juu pada si ile won. Won mo pe OLUWA Olorun lomu won pada sile.



# Esekieli: Okunrin ariran

Itan lati inu oro Olorun, Bibeli

lari ka ninu

Iwe Woli Esekieli

"Iwole oro re funwa ni imole."
Orin Dafidi Ori kokandinlogofa ese adoje

Opin

Itan Bibeli yii so fun wa nipa Olorun iyanu wa t'oda wa ti osi fe ki amo ohun.

Olorun mo wipe ati se ohun ibi, ti ope ni ese. Iku ni ere ese, sugbon Olorun feran re tobe ge tofi omo re kan soso, Jesu, ranse lati ku lori igi agbelebu ki osi jiya fun ese re. Jesu si pada wa si aaye osi losi ile l'orun! Bi o ba gbagbo ninu Jesu ti osi toro idariji ese re, Yi o se eyi! Yi o si wa gbe ninu re nisisiyi, iwo yio si gbe pelu re lailai.

Bi o ba gbagbo wipe otito ni eyi, so fun Olorun wipe: Jesu mi owon, Mo gbagbo wipe ire ni Olorun, o di eniyan lati ku fun ese mi, osi wa laaye sibe. Jowo wa sinu aye mi ki osi dari ese mi jimi, ki emi ki oni aye otun nisisiyi, ati ni ojo kan ki emi kole wa pelu re titi lai. Ranmilowo lati gbo tire ati lati je omo o re. Amin.

Ka Bibeli re ki osi ba Olorun soro lojumo! Johannu ori keta ese kerindinlogun.